MO FI IWE YI JUBA

OLÓGBE

**BISHOP JAMES JOHNSON, D.D.,**

ẸNITI O FẸRAN ILẸ-RẸ

# AKIYESI.

Awọn Owe Ilẹ wa dara pupọ, olukuluku orilẹ-ede ni o ní owe tirẹ, ṣugbọn owe wa ni Ilẹ Yoruba dara gidigidi o si jẹ ohun ti awọn agba wa fẹ lati mã lò, pupọ nigbati nwọn ba nsọrọ nitori a tete mã mú ki itumọ ọrọ wọn yé ara wọn laijẹ pe nwọn nlà a já.

O ti wà li ọkàn mi pẹ lati kó awọn Owe wa jọ, ohun ti o tubọ gún mi ni kẹṣẹ si ati ṣe e ni eyi:

Ni ọdun diẹ sẹhin, mo ranti pe a ni ipade ti o kan ti Fifẹ Ilẹ Ẹni, Bishọp Johnson, ẹniti ng ko ṣẹṣẹ le mã sọ fun nyin pe o fẹran ilẹ rẹ pupọ nitori o ti ja ija rere nigbakugba fun ilẹ rẹ, nsọrọ nipa bi ọpọlọpọ orilẹ-ede ki ti ñ Akin wọn ṣire ti awọn miran tilẹ nsin wọn, o tọka si bi awọn owe wa ti dara to ati bi nwọn o ti jẹ ohun daradara ninu Àṣa ilẹ wa; pe ki awọn ọmọ wa mã ju owe kọkan sinu ọrọ wọn.

Lati igba nã mo tubọ mura lati mã ko awọn owe wọnyi jọ; nitotọ emi kọ ni o kọ ko owe jọ, awọn ẹlomi ti gbidanwo lati ṣe bẹ ninu Almanack tabi ninu iwe itan; ṣugbọn eyi jẹ akanṣe; gbogbo owe wa ni Ilẹ Yoruba kọ li o wà ninu iwe yi, ọpọlọpọ li o wà nibẹ mo si ni ireti pe, bi iṣiri ba wa ngo gbiyanju lati tubọ mã kó wọn jọ ati lati tẹ wọn.

Adura mi ni pe ki ifẹ ilẹ wa le mã dàgba si i li ọkan olukulaku ọmọ enia dudu.

J. A. L.

Dove Cottage,
Ebute Mẹtta.
January 1916.